OWE
A ri teni mo wi a fi apadi fere bo tire mole

# Irohin Yoruba

VOL. IX No 457 MONDAY APRIL 12, 1954 KOBO KAN (1d)

E ma a polowo oja nyin sinu iwe Irohin Yoruba

## Adajo Agba, Olola John Verity Gba Iyi

EKO—Ni ojo Aje ti ise ojo karun osu yi ni ese awon Adajo ati gbogbo awon loya Nigeria pe soso si Kotu Nla (Supreme Court) Ita Tinubu lati se eye idagbere fun Olori awon Adajo Agba (Chief Justice) Olola John Verity ti o ti ise idajo sile patapata lati lo sinmi si ilu re ni ojo ketala osu yi fun igbadun emi re.

Adajo Agba Ogbeni Henri de Comarmond ati Ogbeni A. Mckisack (Attorney General) ati Alhaji Jibril Martin Olori Egbe awon amofin Nigeria so oro aponle pupo nipa Olori awon Adajo Agba ti o fe lati lo si ilu re na bi o ti se je omoluwabi to ati bi o ti se je ki iyi ati opolopo ilosiwaju wa ninu ise Kotu.

Ninu esi Olori awon Adajo Agba na, o so pe on dupe lowo won pupo fun oro iwuri ti nwon so nipa on, o si se alaye pe pelu ilora ni on fi fe fi ilu Nigerin sile ati pe bi ko ba si iranlowo ti nwon fun on nipa ifowosowopo sise na ni on ko ni le da a se de aye ti nwon fi ngyin on yi fun odun mejo na ti on fi sise ni Kotu ile yi.

De ti aye wa fun lati daruko ninu awon Adajo ati Loya ti o pe si ibe ni Ogbeni L. Brett (Solicitor General), Ogbeni C. A. Burton, Awon Adajo Agba, Olumuyiwa Jibowu, Myles Abbott, A. A. Ademola, J. S. Manyo-Plange, L. N. Mbanefo, W. F. Johnson, awon Loya J. I. C. Taylor, H. O. Davies, Oladipo Moore, Rotimi Williams, Iyaafin Adebiyi, awon Omidan K. Agusto ati Rhodes ati Iyaafin Aduke Moore.



Aworan yi ni Olori awon Adajo Agba Nigeria Olola John Verity ba awon Adajo Agba Nigeria ya nigbati nwon nse eye idagbere fun un. Awon wonyi ni o wa ninu aworan na, Maxime de Commarmond, Olumuyiwa Jibowu, Adetokumbo Ademola, Myles Abbott, J. S. Manyo Plange, W. Johnson ati Lonis Mbanefo, gbogbo won je Adajo Agba Kotu Ile yi.

## Awon Egba F'aramo t'Alake

NI ojo keta osu yi ni awon Egba t'ile-toke pejo si Gbongan, Apejo Centenary pelu awon Loya ati awon Ologboni, awon to egba ewe, fun ipade pataki lori Eto Iselu Titun (New Local Government Law). Nwon si se ipinnu pe awon ko faramo awon Ijoye merin ati awon ti o ba wa pelu won lori atako Eto Iselu Titun na

Awon Ijoye merin na ni Oloye I. A. Shodipo, Babasale ologboni awon Egba, Oloye Akinwande Thomas, Oluwo Ipato, Oloye E. A. Odetola Lisa Itoku ati E. A. Lasoju, Balekan Igbein.

Eniti o mu imoran na wa si ipinnu ni Ogbeni E. A. Shyllon, Ogbeni Shitta Agboola si gbe e lese, gbogbo ijoko ipade na si gba bee pe, awon ni igbekele ninu Igbimo Egba "Central Council" ati Alaga Igbimo na Alaiyeluwa Ademola Keji, Alake Abeokuta ati Alakoso Ijoba Iwo-orun Nigeria Ogbeni Obafemi Awolowo fun ona eto ti eto Iselu titun mudani.

Nwon si pinnu lati bere pe ki Ijoba Iwo-Orun tete ba won se ki Eto Iselu Titun na le tete bere. Ogbeni Ayo Rosiji Akowe Apapo Egbe Action Group si ba ipade na soro pe ki nwon mu ise tele imoran ti o le mu ilosiwaju wa fun ilu Egba nipa aise eto pelu awon ara ilu-odi, nipa be e ija le ti ipa be e bes le.

Ogbeni A. Adegbenro si kin in lehin, ki ipade na to tuka.



ALAKE ABEOKUTA

## Gomina Dahomey be ile yi wo

LAIPE yi ni Monsieur Bonfils Gomina Dahomey ati aya re wa se ibewo awon ilu Yoruba, eniti o gba a l'alejo ni Olola Hugo Marshall, Gomina Kekere Ijoba Iwo-Orun Nigeria ati Iyawo re.

Ni enu ipinle (Idiroko) ni Ogbeni E. A. Lewis Ajele Kekere Ibadan [ti o nse bi gbedegbeyo latin Geesi ati Faranse] ati Ogbeni M. C. Atkinson Ajele Kekere Ekun Egbado ti lo pade re.

Ajele Abeokuta Ogbeni I. F. W. Schofield si wa pade re ni igbati yio wo ilu Abeokuta lehinna ni Alake Abeokuta gba a ni alejo o si fun un ni ebun timtim ti a fi ileke se

Awon Egbe Ologun (First Battalion Nigeria Regiment) se eye fun un ni Odan Ibadan, nigbati o de Ibadan. Lehinna ni Olola ati Iyaafin Hugo Marshall si tele Gomina na lo si ile Ife, nwon si fi orisirisi ohun ajeji han an ninu ile ipamo eregbigbe.

Nigbati nwon pada de Oyo Alafin fun un ni agbada etu kan. Ogbeni E. O. Omolodun alaga Igbimo Ijoba Ibile Oyo si ki i ku irinajo loruko Igbimo. Gomina na si dupe lowo won, o si so pe wiwa si ibe yi on yio tubo mu irepo wa larin ara ile yi ati Dahomey.

Ki o to ma a lo, o se ibewo "University College" Ibadan, Olola Obafemi Awolowo si se e ni alejo apeje ti i-mimu.

Eyi ni igba keji ti Gomina Dahomey nwa be ile yi wo. Ti akoko ti o ko wa, wa ninu odun 1950.

## Action Group Mu Ileri Eko-Ofe Se

IBADAN-Ni aro ojo 'Ru ti ise ojo kokanlelogbon osu ti o koja yi ni Olola Obafemi Awolowo so ninu ipade ti "Western Regional Executive Committee" ti Egbe Action Group se pe edegberun [900] awon enia ni Ijoba Iwo-orun Nigeria tiran lo ko awon orisirisi eko olofe, pupo ninu won yio ko awon eko giga ni Nigeria ati ni Ilu Oyinbo.

Olola na si fi han ninu oro re pe Ijoba Iwo-orun Nigeria yio tun ran igba (200) enia lo ko awon orisirisi eko giga ni ofe ninu odun yi. Gbogbo ese awon Iriju Igbimo Iwo-orun Nigeria ni o pe sibe lojo na.




## Obirin Kan Bimo L'emeji Larin Ose Meje

NEW YORK-Obirin kan, Iyaafin Wilbur Chapman eni odun mokanlelogbon ti o ngbe Foxboro Massachusetts ni o bi omo-birin kan ni Chelsea Massachusetts nigbati o di ijo kerinla ti o ti bimo na tan ni awon onisegun tun ri pe oyun tun wa ninu re ati pe ni arin ose marun si ni o si ni lati tun bi omo miran.

Nwon si ti gba obirin na si Ile Itoju awon aboyun ti "United State Naval Hospital." Omobirin

Wo oju ewe kerin

